# AJIRAN ILU OKU [18]

### AYUNORUNBO PADA WA GBA EJE RE

KI Ayunorunbo to de, nwon ti toju ohun ti nwon ti se ileri fun un ki nwon to mu omo Ajiran pon l'ojo kini. Ikopo meji-meji ohun ti nwon se ileri fun Ayunorunbo ni nwon ko fun un, o dupe lowo won, o ni:

Enyin omo Onilogbo, mo dupe, me tun ope da, e seun seun mlubarika, mo dupe, mo t'ope da. E jeki ohun ti e fun mi larin ara nyin. Nko ni nwon fi se, sugbon mo fe wa mo daju bi e o mu ileri nyin se tabi e ko ni mu u se ni. Edumare yio ran nyin lowo ohunkohun ti e ba da'wo le, rere ni yio maa ja si.

Sugbon nko fe ki e gbagbe oro baba nyin. E maa ferau ara nyin tinutinu. Eyi ko ni jeki awon omo araiye le ri nyin gbe se. Nisisiyi, ngo maa pada lo, ara, emi Ayunorunbo, eiye buburu ti nje lawujo eje,



*J. O. SHOYINKA*

* * *

Oniko ika dedegbo, e ko tun le ri mi mo, a fi ti e ba gbo ti e to, ti e si re ipe baba nyin, ni e to le f'oju ganni mi. Olowa ko lora emi nyin. Kabiyesi.

Ige Adubi eleja okun. Iyanja ti ngu gba e ni pe, nkan ti awon ijoye ati ilu ba nfe, ni ki e ma a ba won fe, maşe lowo ninu iti omo enia rubo, eyi lodi si ofin Olorun. K'ade pe lori, ki bata pe lese, emiti o ba ni ki o maşe tire, ise re ko ni s'oju re.

Ebora lo o, o d'ojo miran ojo rere. O poora mo won loju beni Ayunorunbo pada si AJIRAN.

### ABO MI RE O! ENYIN OLUKAWE MI.

Gbogbo nyin ni mo ki lai ku enikan, ni'ojo ti mo ti nko itan mi bo, opolopo ninu nyin ko mo mi. Iro l'enebo, oju ko t'Alafin, emi ni Okunlola, omo Soyinka. Iyeru Okin omo Oloffa-mojo. Olalomi omo abiyu l'oruko. Ilakadi koto Offa. Ija kan, ija kan ti nwon nja l'offa nile Olalomi, oju ta lo se? O sojú ebe loffa, o s'oju aporo ninu oku, iba s'oju oloko o la won. Oloffa ma a la re ko dogba. Ikan ko gbodo ju. Ikan loffa ti ikan ba ju ikan oba ni ko won rororoo.

Mo juba gbogbo awon osewe patapata.

Mo juba gbogbo enyin ti nka itan mi jakejado aabaiye. Olowa nina ano Re ko ni jeki e mo ìsoro nile aiye.

Mo juba Oletu Iwe "Irohin Yoruba" aiye a ye e kale. Ase. Mo tun wa juba baba tobi mi lomo, Alayi Oleidi Olu, Onikanea Aliuon, o b'omi osuru we'da. Orun re o. Iba fun Oloko mi owon Ogbeni S. P. Olopede. O dibo kan na o.

*AKIYESI:—Itan na pari o, ki e ma e reti itan miran lesbara Olorun lose to nbo. Itan na ni "ERIN GOKE ALO" nigbati a ba te Ajiran Ilu Oku tan, e o ri iye oro re ninu Iwe "Irohin Yoruba". Oloku mo dupe o. Enikeni ti o ba fe bere ohun ti ko ba ye e ninu itan yi ki o kowe bere lowo mi. Adiresi mi ni eyi:*

*J. O. Shoyinka 68, Clifford Street, Ebute-Metta. Ngo si da a lohun ti o ba fi stampu kobo meji (2d.) ranse si mi fun idahun pada.*

---

## OSE ATAWOSE LUX
### * Oloorun didun




* Ti a se ni pataki fun itoju awo ara

---




## 'DARAPRIM'

Ero kere kan l'ose kan m'ara won le!

Dabobo awon ebi re lowo Ako-iba atipe ki o ran awon omo re lowo lati dagba dada ki nwon si le lagbara. Awon agbalagba nlo koro kan 'Daraprim' kan l'ose kan, omo ti o ba dagba koja odun marun, idaji koro, ti ko ba dagba to odun marun, idamerin koro. 'Daraprim' ko ladun lenu ko si nyi enia lowo ara yiada.

**O gba'nia lajo, o daju ju, owo re si dinku.**

THE MARK OF BURROUGHS WELLCOME & CO.

---

# Wo işaka rẹ san



Ikunra Mentholatum yio fun e ni itura ti o ba ni isaka. Fara ishe ara-die si 8 Ikunra Mentholatum po ibe. Ko ni si ikunra ti o dara bee.

— ITURA
— IGBADUN
— IMULARADA

Ikunra Mentholatum dabi aseyan ... ti o gba ... gengen o dara fun ... o ngone ... ti ... opolo ... Sa maa le Mentholatum fun gbogbo ... ti o ba ... 

## Sa ma a fi pa ibẹ!



BERE MENTHOLATUM GAN

NINU AGOLO ATI IDE

The Mentholatum Co. Ltd. (Est. 1889) Slough, England

## MENTHOLATUM

* * * * * *




## 'ANTEPAR' YIO LE GBOGBO ARUN-MUJẸ-MUJẸ INU RẸ JADE LOOJỌ!

- 'Antepar' ...
- 'Antepar' ko l'ewu, ...
- 'Antepar' dun l'enu
- 'Antepar' ...




## 'ANTEPAR'
ELIXIR

THE MARK OF BURROUGHS WELLCOME & CO.

---

## Aboyun kan ku somi

IBINI.

NI ojo Isegun ti ise ojo kerinla osu kejo odun yi ni nwon ri oku aboyun kan ti ise Iyaafin Irinagbona Orue, eni odun mejilelogun ti o fe s'oti emi odo Ikpoba Ibini, nwon si gbe oku na lo s'ile iwiti nwon gbe ni la oku fun ayewo ohun ti o pa a.

Lehin iwadi ni nwon ri i gbo pe obirin yi pelu oko re Ogbeni Orue ti wa ninu ede-aiyede kan tele sugbon nigbati o di ojo Aiku ti ise ojo kejila osu kejo odun yi ni nwon wa obirin yi ti n'ile ti nwon si ti ... pe nwon ko ri i titi di ojo ti nwon ... wa ri oku re ... l'odo yi

## Adewale Fashanu jebi

ADAJO Agba ti ejo ti Asoju awon Egbe Alakoso niba Minista ati omina Ijoba Ipinle Iwo-Orun se ka pelu ponun mejilelogorin owo irin-ese.

Ni ojo Aje ti ise ojo ketala osu yi ni Adajo Agba Ogbeni J. I. C. Taylor ti Kotu-nla ni Ibadan se idajo ejo ti Ogbeni Adewale Fashanu towe Iselu fun Ogbeni Gbadamosi Akerele pe Olola Rotimi Williams Minista fun Idajo ati Igbimo Ijoba Ipinle ati Gomina Ipinle Iwo-Orun pe ona ti Ijoba fi yan Rotimi Williams ni Asoju pataki fun fifimo oloye Ijoba Ipinle Iwo-Orun ki ise ona ejo.

Nigbati Adajo na wo bi oran ti lo si ati iru eri ti o wa fun ejo na, o ni on ri si oro Agbejoro Ijoba, Ogbeni A. B. Oki, pe oro yi ki ise on ti kotu le yanju afi ki Ogben Fashanu tun u lo siwaju Gomina Ipinle Iwo-Orun nitori ohun ti o wa ni ikawo ase re ni gege bi ofin eto iselu Ijoba Ipinle Iwo-Orun.

Adajo na si pari idajo re si ori pe Fashanu jebi gbigbe ejo na wa si kotu, nitorina ki o lo san ponun mejilelogorin owo irin-ese fun awon elejo re na ti o niba se ejo.

## Ijoba Ipinle Iwo - Orun fi (£3,000) ran W.A.S.U. lowo

IBADAN.

IJOBA Ipinle Iwo-Orun Naijiria se ikede ni ojo 'Bo ti ise ojo kerindilogun osu yi pe ki awon Ijoba meteta Naijiria yoku ba parapo lati da owo iranwo lowon na fun West Africa Students Union (W.A.S.U.) lati fi ra ile ti o wa ni 69, Warrington Crescent, London, awon yio da egbedogun ponun (£3,000) ni sakasaki odo awon. (Igbimo Ijoba Ipinle Iwo-Orun Naijiria.)

Egbafa ponun (£12,000) ni W.A.S.U. mbebe fun lati gba lowo awon Ijoba merrerin Naijiria. Apapo Ijoba Naijiria si ti se eto egbaata ponun (£6,000) sile fun iranlowo owo Egbe W.A.S.U.

## Ladipo kuro ninu Egbe Alakuko

OYO.

OGBENI Raji Ladipo ti Agbo-ile Ilusinmi, igi lehin ogba Egbe Alakuko (NCNC), Oyo ti fi egbe na sile, o si ti bo sinu Egbe Afenifere (Action Group). O ni ohun pataki ti o mu on fi Egbe Alakuko sile ni pe opolopo awon asiwaju egbe na feran iwa etan.

## Oyanpeju s'ere odun

PRAMKESE, G.C.

IROHIN koto amojuba ni ere Odun Ileya ti awon Egbe Oyanpeju se ni ojo Abameta ti ise ojo kokanlelogun osu ti o koja yi ni dede agogo merin irole ni awon egbe ti bere are, nwon si lo bi kokoro kakiri igun merin ilu yi.

Lehinna ni nwon wa dari si inu agbo-ile baba egbe na Alagba Amusa Olarinde nibi ti awon ti fi jije ati mimu fe awon omo-egbe ati alabaseye lorun. Ogbeni P. A. Oladosu, asoju Iwe Irohin Yoruba ati akowe egbe fi ma onimonamona dabira.

Die ti aye wa fun lati darako ninu awon omo-egbe ati alabaseye ojo na ni awon Ogbeni P. A. O. Oladosu, Amusa Olarinde, baba egbe, Yesufu Folorunso, Emmanuel Adekanye, Raji Sogo, Bashiru Akinbolu, Raimi Popoola, Isaac Adeboye, Iyaafin Asunmowu Olarinde, Ayisatu Oladipo, Rabi ati Rafatu. Aseyi s'amodun.

## E MAA KA IWE IROHIN YORUBA NIGBAGBOGBO









# SALAMI DADA KOMỌJADE

SHAGAMU.

NI ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ ketinielogun osu keje ọdun yi ni Ọgbẹni Abudu Salami Dada ati iyawo re Nimọta ṣe eto aseyẹ ikomọjade ọmọbinrin jojolo ti Ọlọrun fi ta wọn lọrẹ, nwọn si sọ orukọ ọmọ na ni Ajatu Ajimọ.

Alhaji Sadiku ni Alfa ti o ṣe eto isin isọmọlorukọ na ni ọna ẹsin Musulumi. Awọn Alhaji ti nwọn tun ṣe adura nibi eto isọmọloruko na ni Raji, Yesufu ati Sule. Irohin ko to amojuba ni aseyẹ ikomọ na, babu ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ na lọrun bi nwọn ti po to.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Shittu Oni, Jubrila Oni, Joshua Ibisanya, D. A. Famakinwa, O. Ojo, J. T. Idowu, awọn Iyaafin Ajatu Ogunjinmi, Bintu Ogunjinmi, Olubi Jẹminatu ati Ọgbẹni Buraimọ pẹlu Jimọ Baba.

Ki Ọlọrun ṣe ọmọ na ni olori re o. Ki o si fi iru ayọ bẹẹ kari gbogbo awọn alabaṣeyẹ na.






Ẹsanri ati irora lọ!

pẹlu ipara

SLOAN'S

EGBOGI SLOAN NPA IRORA


## Popoọla wa bẹ ile wo

OGBENI Amusa Popoọla Asoju Iwe *Irohin Yoruba* ni Kumasi Gold Coast ati awọn ọrẹ rẹ Salami Akano, Salawu Adeleke ati Gbadamọsi Alade wa bẹ ile Ogbomọṣọ wo.

Ni ọjọ kesan osu keje ọdun yi ni nwọn kuro ni ọhun (Oke-Okun nigbati nwọn si de Eko, nwọn ṣe ibẹwo Olotu Iwe "Irohin Yoruba" Nwọn si ba Olotu f'ọrọ jomitoro ọrọ die ki nwọn to o ma a lọ ilu wọn. Nwọn ni awọn a si fi ara mọ ile fun bi ọsẹ meji ki awọn to tun pada s'Oke-Okun.

# Ọmọ-Ọba Atiba ki Alafin titun ku ori're

ỌMỌ-ỌBA Y. Ade Atiba, onisowo pataki ati oniṣẹ-agbaṣe pataki (general trader and contractor) ni Ibadan, ẹniti o si jẹ ọkan ninu awọn ebi Oba Alafin titun yi lati Ọyọ Ile, ni on fi ifẹ-inu-rere ki enia gbogbo ki Oba Alaiyeluwa Bello Gbadegesin, Orimadegun Ladigbolu Keji, Alafin Ọyọ ku ori're igorioye na.



ỌMỌ-ỌBA Y. ADE. ATIBA

O si tun dupe lọwọ awọn Ọyọmisi fun iduro ṣinṣin wọn ni gbogbo aseko ti ilu Ọyọ fi wa ninu laasigbo ijaigboro eyiti o mu ki irukerudo na mu Alafin ana ti Ijọba ro loye fi lọ se atipo ni ẹhin-odi, ati fun ipinnu wọn lati tete fi ẹniti o to ti o si yẹ si aye Alafin na ni kiakia.

O si tun dupe lọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun pe lori gbogbo iruke-rudo ati tembelekun yi sibẹ nwọn mu ki ilu Ọyọ wa ni alafia, ki eto isẹlu Ijọba Ibilẹ Ọyọ si ma a lọ deede laisi ikunsinu ati pe ti nwọn si fi tun tete gba fun awọn afọbaje Ọyọ (awọn Ọyọmisi) ati fun awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ọyọ lati tete jẹ Alafin titun na ti *o* wa lori oye nisisiyi

Kabiyesi Oba Alaiyeluwa Bello Gbadegẹsin, Orimadegun Ladigbolu Keji, Alafin Ọyọ, k'ade pẹ lori ki bata pẹ lẹsẹ.

## Lucas ati Ṣowẹmimọ di Adajọ

EKO.

LENULỌLỌYI ni nwọn gbe awọn Ọgbẹni H. O. Lucas ati G. S. Ṣowẹmimọ ti nwọn ti wa ni aye adajọ kekere (magistrates) si aye Adajọ Agba (Chief Magistrates) Kotu l'Eko.

Lati igbati nwọn si ti se ikede yi ni awọn ọrẹ, ebi ati awọn ojulumọ kakiri ti nkọ iwe sọwọ si wọn pe nwọn ku ori're ilosiwaju ninu iṣẹ wọn na.

Oye a mọ'ri o.


Awọn Ẹbi Jones wa ni'le ...



Alice Jones jẹ ayanfẹ Anti, inu awọn ọmọde a ma a dun nigbati o ba wa ba won gbe. Nitoripe alaseenijẹ iyanu ni! Ni ọjọ kan bi o ti ndin adiẹ ni ọra adiẹ na ta jo lọwọ. O jo gan an ni, ṣugbọn lẹsẹkẹse ni o yẹ a fi "Cetavlex" pa ọwọ na, o si fi irepe azọ ti o mọ di mọ. Were ni irora na ti lọ, inu ẹnikeni si dun lati ri bi o ti wa o san lẹsẹkẹse.

'Cetavlex'

ORI EGBOGI

*fun iwosan ifarapa, egbo ina jijo ati irora awọara ti ko to nkan, ni kia-kia*



ICI






Wa bi atupaimudani (torch) re ti mọlẹ dara to nigbati o ba fi batiri G.E.C. lo o! Afikun itanṣan yi yio wa titi pe, nitori a de agbara re pa sinu ni.

Fi awọn batiri G.E.C. nikan sinu atupa-imudani re; enikeni o mo pe on lo darajulọ ninu gbogbo awọn iru miran.

The GENERAL ELECTRIC COMPANY LTD. of England

**Ẹ ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba ki ẹ si ma a ka iwe na pẹlu**

## Premier's Office, Western Region.

### Vacancy for Secretary to the Premier and Execueive Council

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Secretary to the Premier and Executive Council, Western Region, Ibadan.

Approximate Salary — Group 4, £2,640 consolidated.

For full particulars see Western Region Gazette No. 40 of 2nd August, 1956, Government Notice No. 624.

Closing date 30th August, 1956.

## Ijọba din Ijoye Igbimọ Eko ku

Lati oju ewe kini

Obakeji Alaga Apapọ Igbimọ-Nla na Mallam Bello Dandogo ni on ri si atunṣe ofin titun na gugbọn on ko fi ara mọ didinku awọn Ijoye Eko ninu Igbimọ Ijọba Ibile wọn. Beni Mallam Maitama Sule, Aṣoju Ilu Kano ati Mallam Nuhu Bamali, Aṣoju Zaria ati awọn ẹlẹgbẹ wọn miran lati ilẹ Hausa so pe awọn ko faramọ didinku awọn ijoye na.

Awọn Ogbeni Kola Balogun ati T. O. S. Benson pẹlu awọn ẹlẹgbẹ wọn ninu Ẹgbẹ Alakuko ran'gun ajọ mọ eto ofin titun yi pe ohun ti o dara fun Ilu Eko ni imarale, ni ki a din awọn ijoye ibẹ ku, ki awọn mẹrin ti o ba si ku nibẹ na ma si l'enu a ti dibo fun ẹtọ eto iṣelu wọn. Nigbati Ijọba fi ọran na si idibo, awọn ti nwọn faramọ ofin titun didinku awọn oloye na ni o pọju awọn alatako lo ni nwọn ba pari re sori ki awọn Ijoye Eko o ma ju mẹrin pere lo mọ ninu Ajọ Ijọba Ibile Eko (Lagos Town Council).

## Aworan awọn ọmọ ti Alabi ji gbe niwọnyi



GANIYU MUSTAFA



MUSIBAU AMUSA



BABATUNDE AFOKE


# ẸNYIN AGBẸ ONIKOKO Ẹ RANTI



## *Ja gbogbo apopo koko ti o ba bajẹ kuro ki ẹ si ma a ri wọn mọlẹ ki ẹ si ma a fun*

## 'PERENOX' TABI 'PEREPOD'

## *s'ara igi koko l'ọsẹ kẹta-kẹta*

## Ki arun korikori ma ba a gbe Koko ati Owo nyin lọ

Ninu awon Garawa oni iwọn ẹsun mẹrinla (14 lb) ni "PERENOX" wa
tabi
Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun meji (2 lb) ni "PEREPOD" wa
Pẹlu oṣuwọn ati iwe apejuwe kekere l'ọfẹ
Didi ni awọn Garawa ogun na wa lati ri i daju pe nwọn wa ni ẹkun rẹrẹ ati pe ko ma fi le bajẹ rara.
Kii pa enia ati awọn Ẹranko l'ara bi nwọn ba loo l'ọna t'nwọn ṣe apejuwe lilo rẹ

O wa kakiri eka ile iṣẹ ati lọdọ awọn aṣoju
THE COOPERATIVE SUPPLY ASSOCIATION
ati
THE UNITED AFRICA CO. LTD

Plant Protection Ltd.


## Ajọmọgbe w'ẹwọn odun marun

ILU IBINI

LAIPE ojo yi ni Adajọ Kotu Ibini ju David Osadiaye, eni odun marundilogoji ara Abule Ughangbe ni Ipberiko Ibini si ẹwọn odun marun gbako, esun re ni pe nitoripe oṣu keji odun yi o ji ọmọ odun marun kan gbe ti oruko ọmọ na nje Amakpoya ara abule Ugboko ni Eku-Ibini.


## CLASSIFIED ADVERTISMENT

IKILO

NIPA AWON ALAGBAFO

Opolopo awọn enia ni nwọn npe ara wọn ni alagbafo ti nwọn a ma a lo gba aṣọ-alaṣọ jọ. Lẹhin nwọn o si gbe e salọ. Eni ti o ba je alagbafo ni tootọ a mu kaadi ẹgbẹ alagbafo Association of Launderers and Allied Trades dani. Nipa nọmba ti nwọn le si ara kaadi na ni o le fi wa alagbafo ti o ba gba aṣọ lọwọ nyin ri. A pe gbogbo awọn memba [illegible] yi ti Ebute Metta fun ipade ni 68 Simpson Street, Ebute-Metta, ni agogo mẹrin [illegible] ojo [illegible] oṣu yi.


Printed by the Amalgamated Press of Nigeria Ltd., 5-7 Apongbon Street, Lagos. Editor: B. M. [illegible], [illegible] Street, Lagos.